# ILU IBADAN MINRINGINDIN FUN OBA GESI




AWOGBA
Omode fun
Girl, Eyl,
Ifiha - ehin,
Orere.
Ra Tire Ni
Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare
Okebola,
Ibadan.
116, Great
Bridge St.,
LAGOS



ELETI OFE
A-NJU WON KO SE WI L'EJO



TO CLEAR
Gents Suede Court Shot,
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6d
Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
19A, Moloney Bridge St
LAGOS.



VOL. VIII No. 454. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 11, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)


## Ilu Ibadan Miringindin Fun Oba Gesi

IBADAN Ọke Ibadan ọlọmu oru, awọn Ibadan gba alejo nla loni ọjọ Satide February 11, 1956.

Latijọ ti alaye ti da aiye, ilu Ibadan ko gba iru fẹ alejo yi ri paapa ni asiko yi ti o jẹ wipe awa enia dudu ni a jẹ alaṣẹ ara wa.

Irohin ko lo afoju ba, eniti o kerin ara, awọn arọ nyọju afoju npatẹwọ alaisan ndide aditi nkọrin asia 'lẹlẹ gba oju ile kan. Ilu Ibadan dun, gbogbo ile ngba ranyin. Ọba ilu Oyinbo pelu ọkọ rẹ wọ Ibadan ni agogo meji abọ, ọsan.

Ọlọla Obafẹmi Awolọwọ pẹlu Gomina Iwọ Orun ati iya afin rẹ lo kọkọ gba Oba ni alejo, lẹhin eyi Alaiyeluwa Ọba Gẹsi ati Ọkọ rẹ yio ṣe ayẹwo awọn Ṣoja ki o to koja lọ si ile ni (Government House)

Orisirisi eto ni Ijoba Iwọ Orun ti ṣe silẹ lati fi ṣe aṣeyẹ fun Oba Obinrin yi ati Ọkọ rẹ.

Ilu Ibadan Miringidi loni Satide.



Queen Elizabeth II

## Iku Oro Niyi

YABA Ha! agbako wo ni yi? Iku oro, iku ojiji, ki Oluwa sọre gbawa.

Orisirisi adura bawọnyi ni awọn abiyamọ ngba ni igbati wọn ri oku ọdọmọkunrin kan ti anpe ni Kuvimọ ninu agbara ojo. Awọn Ọlọpa nwadi ohun ti o fa sababi iku oro yi lọwọlọwọ.

## Aremo Ọba Gesi Prince Charles

Aworan yi niti Aremọ Ọba ilu oyinbo ti orukọ rẹ njẹ Prince Charles. On ni akọbi Ọba Alaiyeluwa Ọba ilẹ Gẹsi. Ọmọ Ọba yi ya aworan yi ni igbati on ṣe ọjọ ibi rẹ ti o di ọmọ ọdun meje. Ki Ọlọrun ki o da si, Kabiyesi Ọba lọla.

## OBA LOLA



Prince Charles

## Ololа Omo Oba Prince of Wales Ni Ilu Ibadan



Aworan inu iwe wa yi niti Ọlọla julọ, ẹ i-ọla nla Oloye Duke of Windsor, ti o wa bẹ ilu wo nigbati o ṣi wa gẹgẹbi "Abidagba" ni ede Yoruba ti awọn Oyinbo npe ni Prince of Wales, (Oba l'ọla).

Aworan yi ni eyiti awọn ya nigbati o mba Ṣoja atijọ kan sọrọ nilu Ibadan, nigbati o ṣe irin ajo rẹ na de Ibadan, ile Oluyọle, ninu ọdun 1925.

Gbogbo iwe iyesi ti iki ni k'abọ ti gbogbo awọn alaṣẹ Ijẹba wa ka fun Alaiyeluwa Ọba Obinrin Elizabeth keji ati Ọlọlajulọ ọkọ rẹ ni awọn m'ẹnu ba irin ajo ti Eni ọla - nla Duke of Windsor yi ṣe si ilẹ Nigeria ninu ọdun 1925.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ọna tara ti enia legba lati di oniṣowo nilẹ Nigeria wa, ni ile ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Ẹnikẹni ti o ba fẹ kan ogunlọgọ aimoye awọn oniṣowo ilẹ Nigeria lara, yala lati ma ta ọja fun wọn ni, tabi lati ma ra awọn ohun ọgọin ilọ wa, ki o lọ si NATIONAL BANK

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch) 1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris. 8/13, King Wil liams Street, London E. C. 4.

## Eyo Adamuorisa

Aworan ti o mbẹ ninu iwe wa yi niti Eyo Adamuorisa ti ao fi se eye fun Adeyeluwa Oba Obiorin ni ojo ti yio fi Eko silẹ pada lọ sibi Oyinbo.

AGOGORO EYO



Asọyẹ oro diẹ ti jmn jade l'ẹnu awọn Eyọ ni a ọc si isalẹ yi fun ẹayin ọkawo wa.

1 Moyọ fun ẹ
Mo yọ funra mi
Emi Alagbada
Osiki ọkọ Sadatu
Hu - ha ha

2 Alẹlẹ e malẹ
Okunkun e makue
Birimu - birimu
Hu - ha ha

3 Emi Ayọnpẹmẹn bi ẹni nyan ode, Awo l'oku l'awo nsisku awo, awọn ogberi a si ma sinku ọgberi ni mode'raye
Hu - ha ha

4 Emi Aworuru, afaruru emi awọ - bi - ere - jano.
Hu - ha ha

5 E mi alakero meji, Ilakunmeji Alakero-meji ni n'ẹọkọ Ibeji
Hu - ha ha

6 Emi Afinju wọja, morin, gore obun wọja pasiọsiọ ẹbun siọsiọ ni o rẹru afinju wọle ni mode 'reyo
Hu - ha ha

### EYI NI ETO EYO ADAMUORISA TI AṢE NI ASIKO TI OKUNNU JẸ OLORI FUN ERE EYỌ NI-'LU EKO

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| 1. | Eyọ | Aina Oba | 2. 3.1892 | 54 | up to the year 1946 |
| 2. | " | Eletu Ijebu | 4. 2.1895 | 51 | " " " " " |
| 3. | " | Tokosi | 10. 6.1894 | 52 | " " " " " |
| 4. | " | Jose Iduumoyinbo | 6. 6.1895 | 51 | " " " " " |
| 5. | " | Idewu Olo | 3. 6.1896 | 50 | " " " " " |
| 6. | " | Iga Misa | 5.12.1896 | 50 | " " " " " |
| 7. | " | Ashongbon Ladoga | 7. 3.1897 | 49 | " " " " " |
| 8. | " | Iga Shasi | 16.10.1898 | 48 | " " " " " |
| 9. | " | Obuiasi | 2. 3.1899 | 47 | " " " " " |
| 10. | " | Ajayi Akanni | 6. 6.1899 | 47 | " " " " " |
| 11. | " | Asi Iya Ajose | 6.10.1899 | 47 | " " " " " |
| 12. | " | Kinyomi | 24.11.1899 | 47 | " " " " " |
| 13. | " | Oba Oyekan | 22. 2.1903 | 41 | " " " " " |
| 14. | " | Sogunro | 25. 4.1903 | 41 | " " " " " |
| 15. | " | Taiwo Olowo | 8. 6.1903 | 41 | " " " " " |
| 16. | " | Iya Oko Ereko | 16. 1.1904 | 42 | " " " " " |
| 17. | " | Idewu Onikoyi | 10. 7.1904 | 42 | " " " " " |
| 18. | " | Iya Bamgbole Shanu | 27. 8.1904 | 42 | " " " " " |
| 19. | " | Onimole Ojuyewa | 6. 5.1905 | 41 | " " " " " |
| 10. | " | Ajayi Obanikoso | 5. 5.1906 | 40 | " " " " " |
| 21. | " | Eletu Ogabi | 11. 8.1906 | 40 | " " " " " |
| 22. | " | Iya Ojora | 1. 9.1906 | 40 | " " " " " |
| 23. | " | Olukolu | 22. 9.1906 | 40 | " " " " " |
| 24. | " | Atin | 9. 3.1907 | 39 | " " " " " |
| 25. | " | Jose Dawodu | 4. 5.1907 | 39 | " " " " " |

### ERE EYỌ TI AṢE NI ASIKO TI IGINLA JẸ OLORI NI EKO

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| 1. | Eyọ | Aluko Onikoyin | 20. 2. 1909 | 37 | up to the Year 1946 |
| 2. | ,, | Fatumọ Ita Martin | 17. 4. 1909 | 37 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 3. | ,, | Aromirẹ Ajyedun | 5. 6. 1909 | 37 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 4. | ,, | Oju Oniyun | 7. 8. 1909 | 37 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 5. | ,, | Aromire Adeṣina | 21. 8. 1909 | 37 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 6. | ,, | Iya Monshibun | 11. 2. 1911 | 35 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 7. | ,, | Faro Apeno | 20. 7. 1912 | 34 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 8. | ,, | Asatu Nukun | 21. 6. 1913 | 33 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 9. | ,, | Red Cross | 3. 11. 1917 | 29 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 10. | ,, | Olori Bamikotun | 29. 12. 1917 | 29 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 11. | ,, | Eletu Alli Dosu | 27. 4. 1918 | 28 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 12. | ,, | Faṣinro Akintoye | 31. 1. 1920 | 26 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 13. | ,, | Ọlalibi Jabita | 28. 2. 1920 | 26 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 14. | ,, | Esugbayi Eleko | 6. 12. 1941 | 5 | ,, ,, ,, ,, ,, |
| 15. | ,, | Red Cross | 20. 5. 1944 | 2 | ,, ,, ,, ,, ,, |

73/S. 2/Vol. VI/18.

## Ministry of Education Western Region

### WESTERN REGIONAL GOVERNMENT SCHOLARSHIPS

The Western Regional Government has decided to bring its scholarships awards for the year 1955/56 up to a total of 100, as advertised in Regional Gazette Notice No. 356 of 1955, by making a further 12 awards for degree courses in Agriculture and Forestry in the proportion of 8 for Agriculture and 4 for Forestry.

2. Applications are therefore invited from suitably qualified candidates of Western origin for awards tenable at the University College as well as in Colleges and Institutions abroad.

3. Suitable candidates already serving in the Agricultural or Forest Department will also be considered for awards provided they hold Grade II Cambridge School Certificates with credit in at least one science subject. All other candidates should ensure that their academic qualifications are sufficient to enable them to be placed in suitable institutions to undertake degree courses abroad, as no sholarships will be offered for pre-University training except to those candidates selected from the Agricultural and Forest Departments.

4. Application forms can be obtained direct from the Secretary to the Western Regional Scholarship Board, Ministry of Education, Western Region, Ibadan Nigeria, or in the case of persons in the United Kingdom from the Office of the Commissioner for Western Region of Nigeria 18, Grosvenor Gardens, London SW.1.

5. Application forms must be returned direct to the Secretary to the Scholarship Board through Heads of Departments in the case of Government employees, and through Principals of Schools or Colleges or through employers as appropriate in all other cases and should be received not later than 29th February, 1956.

6. Central or Regional Ministers must not be given as referees, and applicants who resort to canvassing will be disqualified.

7. Successful candidates will be required to enter into a bond to serve the Western Regional Government for a specified period of time after the successful completion of their courses of study.

## Irora Ehin Didun

Ọna wosan rẹ niyi.
Njẹ o mọ wipe Kidinrin lo njẹ ki ẹhin nsa dun enia? Iti ko ba si ailera fun nibẹ gbogbo idọti ara ni yio ma se danu gẹgẹbi o ti yẹ. Ṣugbọn bi nwọn ba nṣe tikọtikọ idọti ara ti o nwọjọ pọ a ma jẹki ẹhin dun ni.

Aṣẹ egbogi DE WITT'S PILLS yi lati jẹki Kidinrin sise. Isẹ ti a ṣe egbogi yi fun gan niyẹn, yio wo wọn san tan, yio si mu alafia wa fun oluwa rẹ.



O to iwọn adọta ọdun ti egbogi yi ti nṣe iwosan fun enia Ẹhin nro. Aimọye iwe ọpẹ a ti ri gba kakiri aiye. Lọ tirẹ ni sọbu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles


## OKỌ OGUN LỌ SI PỌTA

Ọkọ Ogun ti a npe ni H.M.S. Magpie ti o wa ba wa ki Alaiyeluwa ati Ọlọlajulọ Ọkọ rẹ ku abọ nilu Eko nihin ti fun lọ silu Pọta-Kọtu (Portharcourt) lati lọ se baka nna fun Ọba lọhun. Ọkọ na yio pada si Eko ni ọjọ Alamisi (Thursday) Ọsẹ yi. Ọkọ a refo o





Pelu ayọ ati idunnu ni awọn enia NIGERIA fi ki olufẹ wọn Alaiyeluwa Ọba Obinrin Elizabeth keji ati Ọlọlajulọ Oloye Edinburgh ku abọ.

Ki emi ọla ọ pẹ,
Ki Olorun fi emi gigun, Igbadun ati opo alafia ta wọn lọ're.
Ki emi ọla ọ pẹ,

*Delicious*

# OVALTINE

***the supreme Food Beverage***



### Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.

Just Write, Call Or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN



### Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan

**J. A. AJAO BROTHERS**
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.

ELETI ỌFE
A-NRI-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 25, Kosoko Street, Lagos, P. O. Box 467
CABLES & TELEGRAMS — "ELETI - ỌFE LAGOS" Phone 23370

VOL. VIII. NO. 455 LAGOS, SATURDAY FEB. 11, 1956.

## Egan Ko Ni K'Oyin Ma Dun

Oyin ti ni adun tẹlẹtẹlẹ, ni gbolohun ti a li ṣe akọle wẹsika wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa, lori ọrọ mọsalasi sondoko kan ti awọn kulẹnjẹ Oniwe Irohin ti o ba Alaiyeluwa Ọba Obinrin ilu Oyinbo Gẹsi wa bẹ wa wo nilu wa Nigeria yi kọ ti o jade ninu awọn iwe Irohin ti ilu Oyinbo.

A fi eyi gba ẹnyin enia wa ni imọran wipe ki ẹ maṣe ka ọrọ abuku wọn na si, nitoripe ko si isọkuso ti o le ko abuku ba gbogbo iyẹsi wa ti aṣe fun Alaiyeluwa Ọba Obinrin ati Ọlọla Julọ Ọkọ rẹ, ati eyi ti ao tun ṣe fun wọn nigbati awọn ba pada de si arin wa l'Eko nihin lati awọn ilu Oke-Ọya ati Ile-Orun ti wọn lọ bẹ wo. Awọn Iwe Irohin ti o ni arojinlẹ nilu wọn lọhun ni o ti nkan sara iyin siwa, ki a maṣe wo ti Pẹla ki ijo ma ba bajẹ.

KOSI ALAKARA TO PẸ KI ẸNIKẸJI GBE AGBADA

Bi a ko ba si wo ti Pẹla, ijo ko ni dun, "ẹla l'ọrọ' iyẹn nipe koyẹ ki a ba ọbọ jawere, nitoripe bi ọgbọn enia ba ti mọ, bẹni iṣe huwa. Ohun kan pataki to fun ẹnyin enia wa, wipe ki ẹ fi gb'oju fo isọkusọ wọn bi igbati ẹja ba nsọ ninu odo da, iṣọ, wahala ati iponju ti awọn ilu ọlaju miran fi bi ẹgbaa ọdun ṣe, ni awa ti ṣe, ti a si asumọ aṣeyọri rẹ larin ọdun ti ko pe ọgọrun yi, ẹ ko ha mọ wipe iṣe wa ko le dunmọ awọn aritẹni-mọwi afi apandi fẹrẹ bo tirẹ mọlẹ ninu.

KOSI ALAMỌLA TO MA WIPE TI ON KOYI

Ni ki ẹjẹ ki a ka ọrọ agadamaṣa wọn na si, nitoripe "bi ọmọde ko ba gbọ itan, yio gbọ arọba, arọba ni baba itan". (Owe Yoruba). Bi awọn Oniwe Irohin na ko ba mọ, wọn ko ha ka itan ilẹ ibi wọn nikan bi ẹgbẹrun ọdun s'ẹhin ki nwọn o fi mọ iru ọrọ to tọ ati eyiti o yẹ lati sọ si ilu miran lara. E ma janpata mọ, ẹnyin enia wa, iwa ni yio kilọ fun Oniwa.

ABỌ ỌRỌ TO FUN ỌMỌLUWABI.

WESTERN REGION
PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD.
ARCHITECTS

The Board invites suitably qualified Architects practising in the Western Region and Lagos who may wish to be considered for Board work in the future.

Applicants must state their qualifications and experience and address their applications in sealed envelopes, marked "Architect" in the bottom left-hand corner of the envelope, to reach the undersigned 29th February, 1956.

E. AJAYI,
CHIEF ENGINEER
Western Region Production Development Board.

## Ole L,o Npania

Olẹtu

E jọwọ ki ẹ gba mi laye ninu iwe yin Eleti Ọfẹ. Oleyin mọmọ ni gba latlat awọn ọrẹ mẹta kan wa wọn jẹ ologun, ọdẹ si ni wọn ni ọjọ kan wọn lọ si igbẹ wọn pade Iwin kan oruko wọn niyi ekini Olowo-laiyemọ ekeji Afẹ-aiye. Ẹkẹta ọkanjuwa fẹhinti.

Iwin na si nke iku o, iku o, iku o, wọn si jẹ ọdẹ ti o gboju wọn bere lọwọ rẹ pe ki lo nle ọ lọ? o ni iku ni, wọn si bere pe nibo lowa? o si we ibẹ fun wọn, wọn de ibẹ, wọn si ri apo owo sile mejila. Wọn pinnu pe wọn yio ko owo na wọn si ronu ọna ti wọn yio fi ko owo na ṣugbọn wọn ko ri.

Wọn wa pinu pe awọn yio wa ko l'oru, o pẹ die; ebi npa wọn, wọn si ngbu-ro akuko kan toripe ilu ko jinna mọ. Wọn ran ọkan ninu wọn ọkanjuwa fẹhinti, wọn si sọ pe awọn yio gbe owo na awọn yio pin ni apo mẹfa-mẹfa ti o ba de awọn yio pa pelu ibọn wọn, nigbati o de, wọn yinbọn pa.

On si ti nro ọna ati pa wọn o fi majele si inu ẹmu fun wọn, bi wọn si ti mu ẹmu tan ni awọn na si ku.

Ninu iku ti o npa araiye, iku ti owo gan l'opọju o.

Ki ẹ jọwọ ki ẹjẹ ki ama sọra ninu oju kokoro o.

Emi ni tiyin o
Oluranti Michael

FUN FIFO EHIN FUNFUN DARA-DARA ATI IGBADUN ENU




Ma Lo Egbogi COLGATE Chlorophyll Ti A Fi Nfo Ehin.

Ma fi egbogi Colgate Chlorophyll ti a fi nfọ ehin fọ ehin rẹ nigba gbogbo. Iṣẹ iyanu rẹ ko mọ lori ki ehin rẹ ma bajẹ, ki o mọ, ki o si fun-fun nikan, o tun npa kokoro ehin, ko si ni jẹki akokoro yọ'nu.

Ri daju pe o nlo egbogi Colgate Chlorophyll ti a fi nfọ ehin nigba gbogbo. Egbogi alawọ ofefe ti nbo bi ọṣẹ.




Bere egbogi ti Colgate alawọ ofefe ti a fi nfọ ehin

## Iwa Anikan-jopon npa enia ( apa I )

Lati ọwọ Ẹsọ Ikoyi

Esiun - tunkan, esiun - tukan
Iku pa Erin kiya
Esiun - tukan, esiun - tukan
Iku pa Imologbo
Ko ha wa ku emi ọmọ kekere inu wọn
Ebọ mi ko ru, ẹbọ mi ko gba
Ko ha wa ku ki nlo ku na ? Irẹtẹ eguntan.

Nigba lailai, Eṣu, Ọrumila, ati Ajẹ jumọ nṣe ọrẹ pọ nwọn si nṣe nrin papọ. Bi nwọn ti jijọ nrin lọ si ọna oko kan lọjọ kan, beni nwọn ngbọ igbe buburu kan, gẹgẹbi ti awọn ti o nru oku bọwa awọn mẹtẹta, yara sa wọ inu igbọ lọ, nitoripe awọn mẹtẹta nwọnyi, eriwọ ni fun wọn lati foju kan oku.

Ṣamọ - ṣamọ awọn ọmọ iya mẹta kan ti a npe ni Erinkija, Imọlogbe, ati aburo wọn kekere lo lọ si gbẹ ọdẹ, ti nwọn si pa odidi ẹran Agbọnrin kan, nwọn tẹ ẹran na sori aga, nwọn li aṣọ funfun wo gẹgẹ bi oku. ẹnikan wa gbe ẹran na ru, o nki gbe gẹgẹbi eyiti nṣọkun fun oku.

Bi nwọn ti kọja nibiti Ajẹ, Eṣu ati Ọrumila sapamọ si, eyi Ajẹ dahun wipe, ẹran ni nwọn uru lọ ti nwọn npe loku. Orunmila ati Eṣu ba Ajẹ jiyan wipe, ọrọ yẹn ko le jẹ be rara. Nigbati ariyan jiyan na nfẹ lo wọn ni ki nwọn tẹle wọn lẹhin lọ sile ibiti nwọn nlọ.

Nigbati nwọn gbe ẹran dele, nwọn tilẹkun, nwọn fa ọbẹ yọ nwọn bẹrẹ si kun ẹran na Eṣu parada o di iya arugbo o nkan ilẹkun lati lọ fọn ina, awọn ọmọ iya mẹtẹta na da iya arugbo na lohun wipe ko si aye, awọn nṣe nkan lọwọ. Iya arugbo na si pada. Eṣu tun parada o di ọmọ wundia o tun lọ kan ilẹkun lati fọn ina, nwọn tun wi bakanna fun. Eṣu tun parada o di ọmọ kekere ti nra koro o fi ori ilẹkun wole nwọn si jọwọ rẹ, ori gbogbo ohun ti nwọn ṣe o pada lọ jẹ abọ fun ajẹ ati Ọrunmila wipe, ni nitotọ Pẹlu pẹlu, iru iwa yi ti di ba raku fun awọn ọmọ iya mẹta lati ma ṣe bẹ nigbakigba ti nwọn ba ti pa ẹran nitori ki aladugbo ma ba bawọn pin ninu rẹ.

Ajẹ dahun wipe, pinpin ni ao pin awọn ọmọ iya na pajẹ nitorina ki Ọrunmila kọkọ mu tirẹ ki Eṣu mu tirẹ, emi ajẹ yio ma temi ẹniti ko ba si pa tirẹ jẹ yio di ijọngbọn. Ṣe o ngbọ bayi iwọ orunmila, iwọ sa li olore Ifẹ.

Ki ilẹ ọjọ na to ṣu, ọtutu aburadi kọlu Erinkije, Imọlogbe sare wa da ifa wo lọdọ Ọrunmila. Ọrunmila wi fun pe yio ku dandan ki imọlogbe to pada dele. Erinkija ti di ologbe k'i ọ ọjọ keji to ṣe otutu aburadi tun kọlu Imọlogbe, aburo ẹhin wọn tun sarẹ lọ da ifa wo laifa ọrọ gun Imọlope ku, wọn kita wọn kijẹ tan ni otutu aburadi tun bo aburo wọn.

N'gbana ni aburo wọn bu sẹkun tọ Ọrunmila lati yẹ ara rẹ wo nigbana ni Irẹtẹ Eguten fa soju ọpọa o si ki gẹgẹbi o ti mbẹ loke yi Nibiti o nsọkun yi kiri bẹni o pade Babalawo kan ti o bere bi ẹrọ na ti jẹ o si rohin fun Pẹtẹbi ra sọ fun ki o lọ ko gbogbo ẹran ti wọn yan lori ina wa ẹran yi ni Babalawo na lọ fi bẹ Ọrunmila aburo na ko ku mọ. O wọle, ṣapa ṣapa o wẹ jọpọ jọrọ o njo, o nkọtin bayi Iku re lori mi o re, Arun re lori mi o, o re, Ofo re lori mi o, o re, Iko re lori mi o o re.


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo**

**... ...won omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

**COMMERCIAL MEDICINE STORES**
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS



Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



*Read this list of popular titles*

J.2. 5811 Woro/Ladun Ladun)
,, 5812 Igba Laiye/Moju)
Basiru Alamutu and His (Apala) Band
,, 5813 Ka ma Lufin/Ọrẹ Otitọ kosi)
,, 5814 Amọlẹṣẹ/Fowo Kewe)
Eddie and His Melody Orch.
,, 5822 Adie Ọranyan/Alaimowe
Baṣiru Alamutu.
,, 5859 Asiko/Alake-Lagos
Day Orchestra.
,, 5851 Ologbon/Adekunle Alabi)
,, 5852 Abanijẹ/Raji Mustafa)
S. Ake and His Sakara Orchestra.

J.2. 5869 St. Peter's School/Laisi Adeoti
,, 5870 Njemanze/Nimọta Amoke
Aminu Olaribigbe
,, 5871 Edolo Nosiko Eyinasc-igha-Ijaw Youths' Orch.
,, 5885 Ọpẹ Fun Oluwa/Ọlọrun iṣọla)
,, 5886 Nosiru Seidu/Ọrẹ meji)
,, 5903 Iran Sabarumọ/Ipari Aiye)
Baby Face Mambo Orchestra.
,, 5907 Nwaoba/Eda - Rosy
,, Show Mambo Orch.
,, 5908 Ojure/Aṣakaṣa-
Aminu Ọlaribigbe.
,, 5911 Odele/Odun-Muyili
Adisa's (Were) Band.

*Sold by all the best stores*

HIS MASTERS VOICE

"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

## Mobo Lo Mo Yo

ABIDJAN—Wẹrẹ ni iṣẹ Oluwa Ẹnyin agan ti ko iti ri Ọmọ bi, ẹ ma banujẹ Oluwa nikan ni fun ni l'ọmọ.

A ṣe Ikomọ kan ni ọjọ Saturday 21/1/56 Ikomọ na larinrin l'akoko, a ki Baba ọlọmọ Raji Alade fun ọmọ ti Ọlọrun fi ta yin lọrẹ A si ki Mọriamọ Iya Ọmọ na, o ku ewu o Ọlọrun yio fi ire kari gbogbo wa o,.

Ẹnyin olotu na Ọlọrun ko ni jẹ ki irohin bayi wọn yin ninu Eleti-Ọfẹ amin.

Alufa Malam Yesufu lo ṣe suna fun wa nibi Ikona, lẹhin na, Alhaji S. O. Oloyede l'oṣe wasi fun wa, lẹhin eyi, abẹrẹ si bọ'ọmọ yọ pẹlu ijo pẹlu ilu, a ki Salu aburo baba ọmọ nipa Refrigerator rẹ to fi silẹ fun siṣọ ọti di tutu, ẹ ku inawo omi inu igo ati jijẹ.

Ọpọlọpọ enia l'owa sibẹ ikomọ na ni ilu Tiassale ati Abidjan.

Wọn ti pọ lapọju tojẹpe a ko le darukọ wọn Karimu Oyelami lo ṣe olori wọn wa pẹlu Mọto mẹrin, wọn gunlẹ si ọdọ wa l'ayọ

Baba ọmọ ki Jinadu Ojo ati Jimọh Oyẹtunde, Ben Ajao, Ṣitu Ọla ati Ẹnyin yoku na pẹlu akọwe J. A. Fasinya, Ẹ ku abaṣeo adun yio kari o, lọkunrin Ọmọ lao ma gbe jo o.

## Irohin Ile Ejo

Ni Kotu Sant-Anna ni Adajọ H.O. Lucas ju akọwe kan ti owo oṣu rẹ jẹ £8. s'ẹwọn ọdun mẹta fun ẹsun ole jija.

Akọwe na ni oruko rẹ njẹ Sunday Otakpu, bi ọmọ ọdun mejilelogun ni ọjọ ori rẹ, adajọ gba wipe o jẹbi ẹsun irin'wo ponun (£400) pelu iwe ifi-owo-si Banki ti nwọn fi sun.

Adajọ si tun sọ wipe o to asiko ti awọn ọdọmọde wa ti nwọn ba fi si aye ipo iṣura ni lati kọ lati ma ko iriju ba wa loju awọn ajeji, o si tun wipe fun igba ti o ku ti on ma ṣe lori aṣẹ idajọ, ọdọmọde, yowu ti nwọn ba muwa siwaju on fun sun ole bi iru eyi, on yio da ẹjọ gbigbona fun ẹnibẹ.

## Ore Soro Ni Sise

BRICKFIELD E.B.—Anu ṣe ni gidigidi lati jihin iku Ọgbẹni Shokunbi ẹniti ọgbẹni Ijẹsha kan ti o nṣe iṣẹ barber ṣa ni ẹhin ọrun eyi ti o si ṣe iku pa Ọgbẹni na lowurọ ọjọ 8th oṣu Feb. 1956.

Bi a ti gbọ idi ọrọ na si niyi Ọkunrin Ijẹsha ti o nṣe Berber yi, ko ni ile ti o le gbe, lori epo igi ti nwọn sa sinu orun ni o nsun. Nigbati Ọgbẹni Shokunbi ri, anu ṣee. o si wi fun ọkunrin na pe ki o si ma wa sun ninu ile ti on ṣeṣe nkọ lọwọ ni Briki ọkunrin ọdaran yi si ti nsun nibi ti nwọn fi si yi le ni ọdun kan abọ

Asiko to fun Ọgbẹni Shokunbi lati fi ọda kun ile rẹ titun yi, o si wi fun alejo rẹ ki o yẹra. Otan Awe, ọrọ ko ja eyi lọ, ni ọdaran yi ba taku pe, on ko ni kuro. Bi Ọgbẹni Shokunbi ti nfẹ wọ Mọto lati ma pada sile, nṣe ni ọkunrin barber na bu ni adá ni ẹhin ọrun

HA! ORE SORO NI ṢIṢE

## Soja Atijo W'ewon olobinrin pupo.

LONDON, ITAN Ọkunrin yi berẹ ni ọdun 1938.

Ni Kotu Old Bailey ninu Ọsẹ yi ni nwọn ju YALLOP s'ẹwọn oṣu mẹsan fun ẹsun ik'obinrin jọ ati wipe o purọ lati le gba iwe ọkọ (Passport).

Ọgbẹni Yallop yi jẹ ọmọ ọdun mẹtadinlogun ti o ngbe ilu Norwich, Soja atijọ ni iṣe. Ninu ọdun 1938, o gbe ọmọdebinrin kan ni iyawo oruko obinrin na ni Lilian Hewett. Wọn bi ọmọ meji ṣugbọn nwọn pinya nigbati ogun ara pa ni Dunkirk.

Yallop tun ba Rebecca Macgregor pade Ruislip, o tun gbe ni'yawo, nwọn tun bi ọmọ mẹta.

Ninu ọdun 1951, Yallop lọ silu Kanada o ti ibẹ de Nassau, o ti le sọ ara rẹ di ara ilu na. Nigbati ọwọ tẹ, Loya rẹ sọ wipe ọti mimu ni o nda l'ama, Odidi, Ọsẹ mefa ni o fi mu ọti para ni asiko yi ni o gbe iyawo miran o si ba fo lọ si Kanada nwọn bi ọmọ kan iyawo pada lọ silu Bahamas.

Kete, lẹhin eyi ninu ọdun 1953 ni o tun ba arabinrin kan pade ni Ontario, oruko eleyini a ma jẹ Omidan Marian Sharpe, ọmọ ọdun mẹtalelogbọn.

**Polowo Ọja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ọfe**




**ODA TI OBA CDE ISINYIN !**

**PAMMASTIC Ki nse Oda sa O ni ogun ninu Kia kia ni osi ngbe, kio tete sa, on lo dara ju fun ile wa**

PAINT DEPT
Elegbata Marina,
Lagos.
Phone 23826.

S.C.O.A.

PAINT SHOP
LAGOS
Phone 20507/8
extension 6 & 7

B/S. 2/Vol. VI/980.

## PUBLIC NOTICE

It is hereby notified that the Ododua ceremonies and plays known as Agu'Osa will take place at palace ground from 19. 2. 56 to 26. 2. 56.

**AKENZUA II**

Oba of Benin

## Are-Oko Fe Ri Oba Oyinbo

(RERIN DIE)

Okunrin ara oko kan ti o gbo wipe Oba oyinbo mbo wa si ilu Eko mura lati wa foju ri Oba na nwon si ti so wipe enia ko gbodo wo aso idoti lo ti pade Oba

Iyawo Nibo ni e ti'e nlo ti e di gaga, ti e di gogo bayi

Ara oko Ara ni iwo nitoto tabi iwo ko gbo wipe Oba oyinbo mbo nilu Eko loni, ko si gbodo ri enia ninu aso Idoti. Wo', mo ti ra asia temi lati fi ki k'abo.

Iyawo Bi o ba je wipe iwo logbon jojo se iwo yio sunmo eti ilu Eko na ki o to yan aso sara Buso mefa ni iwo yio rin pelu irin pakaleke, ki o si ranti wipe ori afara ko se gun pelu ikanju ati oso daradara bayi, o ko ba ni bo ewu yi sile ndan?

Ara-oko:- Jowo fi mi sile o jare, emi omode ndan, tabi oni ni mo ti nrin l'ori afara?

Iyawo:- O dara, oju mi ko su le gba. Jeki nran o lowo e u re yi koja lori afara.

Are-oko Ehen! nibo lo ti fi oruko si ti o nje Labotki?

Iyawo:- Jowo se pelepele nibiyi o, nitori afara na ryo jojo

Ara oko:- Sa ma niso, ko sewu, ko nye oni mo ti nru eru gori afara ti o mbe lona Igando, sa ma niso. Ye! ye! ye! Iyawo mi tete mu mi dani, mo nfe subu O di gbabu! ninu ira.

Iyawo:- Bu si erin, o kigbe Ha-a-a! ohun ti mo wi ti o wipe eau mi ruo niyi o?

Ara-oko:- O tile ya mi lenu bi afara yi se ni lati gbe mi subu afara ona Igando ati ti Itire o ma yo ju eyiyi lo, ere ni mo nsa lori lori won

Iyawo:- Jowo ma tete dide o jare, Oba ma fere de na,

Ara-oko On lo mo, jeki o ma lo, nko le wa ku sidi oba ti ko mo mi ti ko si ni fun mi lepinni.

Iyowo:- Ke, ke, ke, erin pa mi titi mo yi subu gbirigbiti ooro re yi pami leru ju Kurumo. Talo tile ranse pe o?

Ara-oko Nko ma mo, nko mo eniti oran Belu wo oko.

### Ab'ese Ku Bi Ojo Hogan Kid Bassey

Hogan Bassey tun se kau si, Ni s'e ojo Tuesday ose yi ni Hogan "Kid" Bassey tun ja aja bori pelu ogbeni Sneyers ara ilu Belgium.

Nigbati o di ayipo kerin ni Bassey pari gbogbo agbara Sneyers ti ko le fi ara da ese Bassey mo, ni jagun ba f'ehin sile, Bassey ti fi ese fa imu re ya.

Eyi fihan wipe Hogan "Kid" Bassey nsare ije lati gba Oye nla fun ese iju

### Ni Iranti Oninure

Ni iranti iya wa, ologbe

MARGARET BOLAJI,

MARTINS

eniti o se alaisi, ni odun Kerin s'ehin, 8th, February 1952.

Ti a sin a l ojo keji 9th Feb. 1952

HA ! Iya wa owo eniere

Alake Opo,

Opo Onireta,

Orun rere O.

Awa omo re:-

Modupe,

Yemisi,

Akinmnde

## ORIKI BAMWO




Bamwo de,, alajela omode, agb'omola bi orisa, akokoluko ogun nda'mo l'ekun igbona, atata ogun ti np'otutu re wa-rawara, a je bi idan, a gba bi etu ibon. O s'ahiku dikugbagbe, o s'omo ti nhehin l'ore, Iko ri i sa, Iba ko l'ona tagiri, aiperi ri i d'ekun iyoon. Olugbala f'omo ti nyagbe orin, o kapa inu iwo, o lu jedi l'afupa, gbogbo abiyamo nyo sese, Ela ri i o roju, Orere ri i o na'gbe bo'ra, Eyi npa'lemo lodileso, Ore Ikoko, kosemani awon abiyamo, eni araiye njjadu ra.

O de'lu Ibo, o do'ga, o de'le Hausa, o d'oba. Gbogbo Onisegun l'o so pe ko l'egbe, gbogbo omode l'o nfe e fun'lere.

IGO KEKERE 2/6d.

IGO NLA 4/6d.

owo oko 1/6d fun igo kan.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street,
P. O. Box 2,
Ebute-Meta.

No. 38

## PUBLIC NOTICE

FEDERAL MEDICAL SERVICES

VACANCIES FOR STUDENT NURSES OR MIDWIVES

Applications are invited from girls with General Schools Certificate, Secondary Class III and IV Certificate and Modern II Certificate for training as Nurses or Midwives. Preference will be given to Candidates of School Certificate Standard.

2. Those who are accepted will enter the Nurses Preliminary Training School, Lagos, for a 6 months' course which will commence in April 1956. During this course, students will be required to reside in a Government Hostel or in an approved lodging house. A subsistence allowance at the rate of £7 a month will be payable and where maintenance is provided a charge of approximately £4 a month will be made.

3. On completion of this Preliminary course, successful students will be appointed as Probationer Nurses or Pupil Midwives in the salary scale N. 1 which commences at £150 a year. They will be posted either to the General Hospital, Lagos for training in General Nursing or to the Massey Street, Maternity Hospital, Lagos for training in Midwifery.

4. Candidates are required to forward the following documents with their applications which should reach the PRINCIPAL MATRON, FEDERAL MEDICAL HEADQUARTERS, LAGOS. before the 26th February, 1956

(i) Copy of Certificate of Education.

(ii) Copy of Birth Certificate or of a Sworn Declaration of age made by Parent or Guardian

(iii) Copies of 3 recent testimonials, one of which should be from the Headmaster of the last School attended or from the most recent employer.

5. Only those candidates who are selected for interview will receive a reply.

**Polowo Oja Sinu Iwe Irohin Eleti Ofe**

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 23 Kosoko Street P.O. Box 447 Lagos Phone 23376